# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL. XIV NO 876 LAGOS SATURDAY JULY 6 JULY 12 KOBO MEJI (2D) 1963


EYI ARA:

# Oku Arugbo Kan Taji Lowo Aweku Lojiji

OHIO (USA)—Ni ilu kan ti nwọn npe ni Willard ni Amẹrika ni a gbọ irohin nipa iya arugbo kan, Mary Voight, ẹni ọgọrin ọdun ti o jalaisi ninu ile awọn alaisan kan nwọn ti ntọju rẹ ṣugbọn nigbati nwọn gbe oku rẹ dele ti awọn aweku bẹrẹsẹsi wẹ ẹ lati ṣe ọlọjọjọ rẹ fun sinsin ni o ba taji mọ wọn lọwọ.

Warawere awọn ti o nwẹ ẹ na ti ju ikanrinka ọwọ wọn silẹ, nwọn si fẹsẹ fẹ ẹ. Eleyi jẹki iya na fura, o bẹrẹsi ber: lọwọ awọn diẹ ti nwọn ṣe igboya lati duro wo o loju si daradara wipe kilo de.

Awọn na ko fi ikan pe meji, nwọn tete pe mọto kan wipe ki o ba wọn ru iya na pada si ọdọ awọn dokita ti o ntọju rẹ ni ile alaisan ti nwọn npe orukọ rẹ ni Willard Memorial Hospital.

Ọkan ninu awọn dokita ti o wa nibiti awọn gbe ntọju rẹ, Dokita Richard Jackson ni ni oju on ni ya na ṣe ku ninu iyara ti awọn ti nfun un legbogi. O ni awọn wo o titi, awọn ri wipe ko le mi rara mọ ati pe awọn ri wipe ẹiẹ ara rẹ ko ṣe iṣẹ mọ rara ki awọn to sọ fun awọn ara rẹ wipe ki nwọn wa gboku rẹ.

Dokita na ni o ni lati jẹ wipe siso soke lojiji ti mọto ti nwọn fi gbe oku rẹ na lọ sile ni o mi i sihin sọhun, ti o fi ẹ ki iya na tun taji saiye. A gbọ wipe ti njẹun dẹ diẹ nisiiyi.


## LAGOS RACE CLUB
## AUGUST MEETING 1963

SATURDAYS 27TH JULY, 3RD, 10TH & 17TH AUGUST, 1963

Provisional Programme and Entry Forms can be obtained on application to the Secretary, P. O. Box 51, Lagos or at the Race Course, Lagos.

Note—No Entry fees will be refunded after the draw has been made.

Entries close at noon on Monday 15th July, 1963.

No Cheque will be accepted.

C. H. E. MILLER
Hon. Secretary.


## Onimoto Fi Aja Ponun Mewa B'ogun

IBADAN-Baba Onimọto ayọkẹlẹ kan ti orukọ rẹ njẹ Joseph Maiyero, ti o nṣe iṣẹ onisowo ni a gbọ wipe awọn ọlọpa Ibadan mu lọ si iwaju adajọ Kotu kan ni ana pẹlu ẹsun wipe o fi mọto ayọkẹlẹ ti o fi nṣe faaji pa aja ni Bẹrẹ.

Nigbati nwọn ka iwe ti awọn ọlọpa kọ ẹsun ọgbẹni na si fun un, o ni ki nwọn ma fa ọrọ na gun lọ titi on jẹbi ki adajọ ko darijin on, esi ni ọrọ na ṣe.

Agbẹjọro awọn ọlọpa ti o tako ọdaran na ṣe alaye fun adajọ wipe iwakuwa ti o wa mọto rẹ ni o jẹ ki o pa aja na ti olowo rẹ npe ni BEN nipa ku-pa.

Adajọ ti nwọn nṣe ẹjọ na lọdọ rẹ wa fi apara bi baba onimọto na lere wipe ko da on loju wipe o fi aja bọ OGUN fun mọto rẹ ri lati ọjọ ti o ti ra mọto na, nitorina ki o lọ san pọnun mẹwa sarai si apo Ijọba fun aja ti o pa bọgun ni Bẹrẹ yi.

## In Memoriam

-X-X-X-

In loving memory of our dearly beloved father, the late Abudu Lasisi Dabiri, the Baba Adinni of Lagos, (1941–53) who slept in Allah on Friday 3rd July, 1953. Ten years have rolled by since you answered the call of Allah; but to die and live in the hearts of those behind is not to die.

We leave thy soul to rest in peace with Allah.

Remembered by Muhammed Mustafa Dabiri.

On behalf of the family.

# Awon Olo-sa Gbogun Ti Awon Olopa Enu-gu

ENUGU—Awọn ogboju ọlọṣa ti gbogun ti awọn ọlọpa Enugu ti nwọn ngba ọta ẹrọ lati tuna aṣiri iṣẹ buruku ti nwọn nṣe kakiri loru. Ju gbogbo rẹ lọ awọn olori ọlọṣa na ti nwọn fi ara pa wa ni ile alaisan ijọba ni Enugu nisisiyi.

Gẹgẹbi irohin ti a gbọ lati ọdọ onirohin wa, labẹ kereni Asata ni awọn ọlọṣa yi fi ṣele, ti nwọn ma nsa si, ṣugbọn ti o ba di oru ọganjọ nwọn a yọkẹlẹ jade lati ma da'na, awọn miran a lọ si arin ilu lati ma ko ile onile.

Nkan ti o fa ija ọsan-gangan yi ni ti ọga ọlọpa kan ti o ni on ni lati mu ọkunrin alagbara olori awọn ọlọṣa na ti oruko rẹ njẹ Okoli Uchocukwu, ti o ni ẹnikan ko le mu on rara ninu iṣẹ ole ti on nṣe.

Nigbati ọga ọlọpa yi de ibiti o gbe sa pamọ si nwọn fija pẹta pẹlu awọn enia rẹ. Awọn ọlọṣa wọnyi gba gbongbo lọwọ awọn ọlọpa, nwọn bẹrẹsi koo bo wọn.

Awọn ero ti nwọn pejọ lati woran ni nwọn gba awọn ọlọpa na lọwọ awọn ọlọṣa yi; alubolẹ ni nwọn fẹ lu wọn.

Ọlọpa kan ti oruko rẹ njẹ Kalu Ibe ti awọn ọlọṣa yi ṣe ni jamba wa ni ile alaisan nibiti awọn ti ntọju rẹ nisisiyi.

# Alhaji Ilorin Pade Agbako Iku Moto

OGBOMỌSHỌ— Ọlọrun maje ki a rin lọjọ ti ebi mpa ọna; awọn ero inu mọto akero Alhaji Ilọrin pẹlu Alhaji onimọto alara paapa rin lọjọ ti ebi mpa ogun lọna Ogbomọshọ ni owurọ ijẹta.

Ninu awọn ero mejilelogun ti ọkọ akero na enia meje ni awọn ku bamu bamu nigbati mọto na, kọ lugi ni ọna Oshogbo mọ Ogbomọshọ; awọn ero mọkanla yoku si wa ninu nwọn npọka iku lọwọ ninu ile-alaisan Ogbomọshọ ti nwọn ru wọn lọ.

Awọn enia meji ni awọn ọlọpa ṣẹṣẹ ri ninu awọn oku na ti awọn ẹbi nwọn wa gboku wọn. Awọn ọlọpa si ti fi iwe ikede sode wipe ki awọn ti enia wọn ba wọ mọto ni ijẹrin ti nwọn ko de ibi nwọn ba nlọ, ki nwọn wa wo awọn ti o ku sọna Ogbomọshọ.


## Akiyesi

..Nitoto Oja Ko Ta Ni Akoko ti a Wa yi...

Sugbon aita oja ko si fun awon ti nwon npolowo oja won sinu iwe,.

Irohin ELETI-OFE ni osose.

Kowe Ipolowo Oja tire ranse si ELETI-OFE

28, KOSOKO STREET, LAGOS.






## Onimoto, E Sora Loju Ona Titi

## Eleti-Ofe D'araba

**Ejo Aunti "Koforun"**

# Awon Olopa Mba Baba Alarina Sejo Ni Kotu

LONDON — Boya ẹnyin ọkawe jwa niran irohin kan ti a te jade laipẹ yi nipa minisita kan ni ilu Oyinbo ti o ju iṣẹ rẹ silẹ nitori ọmọge kan ti a pe ni aunti "Koforun" ọrọ ọmọdebinrin na ti bigo badubi nisisinyin tobẹgẹ ti awọn ọlọpa ilu Oyinbo ti mu ọkunrin kan ti awọn npe ni Dokita Stephen Ward, baba alarinna, ti nwọn sọ wipe ninu iyara rẹ ni awọn ale ọmọbinrin yi ti nlọ pade rẹ.

Ejọ ti nwọn mba Dokita Ward, " baba alarinna" ro ni pe awọn aṣẹwo pansaga ni o fi npa owo. Ejọ na jẹ pataki pupọ ti o fi jẹ wipe gbogbo awọn araiye ni o fẹ mọ bi ọrọ ejọ na ti nlọ si, nitori eyi ni a ṣe sọ fun onrohin wa ni ilu Oyinbo wipe ki o maṣe fi ọkan di wa leti ninu bi nwọn ba ti nro ejọ na si.

A gbọ wipe nwọn bẹrẹsi ro ejọ na ni Kotu kan ni ilu London, aunti Koforun, Omidan Christine Keeler paapa ni awọn ọlọpa kọ pe wipe ki o sọ tẹnu rẹ niwaju Adajọ Kotu na.

Ẹsun mejọ ni awọn ọlọpa ka mọ Dokita Ward, Oyinbo ti awọn pe ni baalarina lẹsẹ; nwọn ni ninu awọn obinrin wundia ti o nko fun ọkunrin ni ọmọge kan ti nwọn npe Marilyn Rice-Davies ati awọn obinrin miran.

Nigbati aunii Koforun ọmoge Keelerbọ sinua pot ti ẹleri ti o bẹrẹsi ro ejọ o ni on mọ Dokita Ward ti awọn ọlọpa mba ṣe ejọ daradara, o ni bi ẹgbọn n

o nṣe si on, O ni ti dokita na ko fi igbakan yan on ni ale tabi ki o ba on lọ bi alẹ rẹ ri.

## Owo Ile

Ọmọge na ni on mọ Ọgbẹni Profumo, Minisita eto awọn jagunjagun ti o fi iṣẹ rẹ silẹ nitori ẹrọ ti o dele yi. O ni o yan on lale, o si fun on ni owo o ni ki on ma mu u fun iya on.

Nigbati agbẹjoro Ọba, Ọgbẹni Mervyn Griffith Jones bere iọwọ ọmọbinrin na bi ko ba fi igbakan yan ọkunrin ara (Rọssia) kan ti orukọ rẹ njẹ Invanow lale, o ni nitotọ ni, gbogbo Kotu kun hun, hun.

Agbẹjọro Ọba ni owo ile ti ọmọ na pẹlu ọrẹ, Marilyn jọ ngbe nkọ, ṣe nwọn nri owo ṣe to ninu iṣẹ aṣẹwo ti nwọn nṣe lati fi san owo ile na; O dahun, o ni awọn nsan an.

## Tegbon T'aburo

Lọya na wa tun bi i ler wipe iani o nfun w a lowo ti nwọn fi nsan owo ile na; o ni awon ko mọ, o ni Dokita Ward baba alarina a ọa ni nsọ fun awọn wipe nwọn ti san baba onile na.

Nigbati agbẹjọro yi fi oro wọrọ lẹnu rẹ titi o daruko Ọgbẹni Ọlọla kan ti nwọn npe ni Lord Astor, o ni on ni o nsan owo ile ti awọn ngbe na fun awọn mejeji. Omidan Keeler ni ọrọ on pelu Dokita Ward ti di tegbọn taburo nitoripe on ko le ṣe ki on ma de ọdọ rẹ lọjọ kan.

## Ijo Koforun

Ọmọdebinrin yi sọ fun adajọ wipe ninu ile faaji kan ti nwọn npe ni ile ere MURRAY ni on ti ṣe alabapade Dokita Yard. O ni ịchiati awọn ti pade dokita yi ko jẹ ki on sinmi, ojojumọ ni o nfi ẹrọ gbogbohun ba on sọrọ lọdọ iya en, o ni on paapa tilẹ wa silẹ awọn nigba kan.

Keeler ni onfi ṣigba kan ko lo si ọdọ dokita yi ni Orme Court lati ma ba gbe o ni on a ma ba awọn ọrẹ dokita na ti nwọn ba ba a wale ṣere, ṣugbọn on ko ti ma GBEṢẸ pẹlu ẹnikan ninu awọn ọkunrin na rara ni gbogbo igba na. O ni on tun fi igba kan pada si ẹnu iṣẹ no Koforun on ni ile faji Murray.

## Omo ... -Sun-Ta

Omidan ... er ni n bẹ ni on gbe ti pade ọrẹ on kan ti oruko rẹ njẹ Marilyn Rice-Davies pẹlu ọmọkunrin kan ara ilu Persia, awọn jọ wa ngbe pọ. O tun ṣe alaye wipe Dokita Ward ma wa awọn wa sbẹ pẹlu awọn ọrẹ rẹ.

Keeler ni on niran wipe on fi igba kan bi osu mẹta gbe ọdọ ọmọ ara Persia yi ki on to ko ẹru on kuro lọdọ rẹ lọ si ile Dokita Ward ni 17 Wimpole Mews, London lati ma gbe.

Aunti Koforun yi ni on mọ wipe dokita fẹran awọn ọmọge alọmọ on ma npe awọn ọrẹ on ti nwọn ba wa on fun nu nigbakugba.

## 'Koforun' Keji Ni On Fe Para On

London-Aunti Koforun keji, Marilyn Rice-Davies ti omidan Keeler ni tos pelu rẹ ngbe pọ, ti awọn ọlọpa pe ni ẹleri wipe ki a wa sọ tẹnu rẹ ni on fẹ para on nigba kan ninu ọdun ti o kọja, o ni ko nṣe nitori ọkunrin Oyinbo kan ti nwọn npe ni Peter Rachman ti on mba gbe ti o jalaisi lojiji ti ko fi kọbọ silẹ fun on; Marilyn ni on mọ nkan ti on ro de ẹ ki on to sọ wipe on fẹ ku.

## ...Bo Lasiri

Awọn ọlọpa fi orukọ bo ọmoge koforun kan ti nwọn pe ni X, ti o tun jẹri ni Kotu lasiri; ọmọgbe X ni lọjọ ti o pade Dokita Ward on ni ki on wa wa nkan ribiribi ti o ṣe siuu iyara on ti on ngbe, o ni dokita yi ni on fi jingi ẹgbẹ meji sile ti jẹ wipe bi awọn tokọ taya ba ntage enia le ma ri wọn.

Ọmoge X ni on sọ wipe on ko fẹ ma wo iru ere iṣekuṣe bayi, o ni dokita na owo wa ninu

(Wo yoku loju ewe kẹfa)

YOUR SPECIALIST FOR ALL
BUILDING MATERIALS
BROSSETTE
(NIGERIA) LTD.
WHARF ROAD - APAPA - (NIGERIA)
P.M.B 1135 - APAPA
At your service
• STOCK
• SPECIAL ORDERS
• TECHNICAL INFORMATIONS

BE TALLER
Increase your Height.
Details free. Add:-
C. T. Hospital, Azad Market,
Delhi 6, India.

# ELETI–OFE

(A NJU WỌ N KOṢE WI LẸJỌ)

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAM
28, Kosọkọ Street, Lagos. "ELETI-OFẸ" LAGOS

P. O. Box 467 Phone 23370
VOL. XIV. NO. 876 SATURDY JULY 6 — JULY 12 1963


## Oro Olotu:

# Awon Oni-moto Tasi Npase Oni-kunmo

'TS Awọn Yoruba ni bi ko ba si ofin ẹṣẹ ko si, ṣugbọn orişirişi ofin lo wa. Iru ofin ti awọn onimọto akero ti awọn npe orukọ wọn ni tasi l'Eko wipe awọn fẹ ki ọga ọlọpa fọwọ si wipe ko si mọto akero kan ti o gbọdọ ti ọna Mushin wa ba awọn kero l'Eko ni a le pe ni AṢẸ ONIKUMỌ
Kunmọ nikan kọ ni ofin ti awọn fẹ ki awọn fọwọ si fun awọn yi mu dani, o di ọfa mọ ẹru pẹlu nitoripe awa oniwe irohin yi bi a ti kiri gbogbo idalẹ to, a ko ti gbọ iru ibiti awọn alamojuto Ijọba ilu gbe fọwọ si aṣẹ anikanjọgpọn bayi.

### Anikanjopon

Ko si nkan ti o fa ti awọn dẹrẹba awamọto yi fi nfẹ iru ofin anikanjọpọn bayi ju ọkanjua ati iwa kẹnimani lọ.

Ti ẹnyin ọkawe wa ti o nhaya mọto tasi ba ṣe akiyesi lati igbati Ijọba ti paṣẹ si i wipe gbogbo mọto ayọkẹlẹ ti nwọn ba ti nlo gẹgẹbi tasi ni o ni lati ma ni ẹrọ ikawo (meter), ẹ o ri wipe lati igbana ni ọgbọn arekereke awọn dẹrẹba yi ti pọ si.

Nwọn mọ ọna ti awọn le lo lati tu awọn ero ti nwọn ba ko jẹ.

### Ibadan Nko?

Kilo fa ti ero ti nwọn ba gbe lati Idumọta de Ẹhingbeti ko gbọdọ san ẹgbaa (6/-) tabi ẹgbẹdogun (9/-) nigbati o jẹ wipe ero ara Ibadan ti o ba wọ mọto tasi lati GBAGI de Ọja'ba n'Ibadan ẹgbaa (sisi) ni yio san?

Ẹ wo iye igbati Gbagi de Ọja'ba ni Ibadan fi jina ju ati Idumọta de Ẹhingbeti l'Eko lọ. Ju gbogbo rẹ lọ, a ṣe ikilọ fun awọn alaṣẹ ijọba wa l'Eko ki nwọn ma gba ọjẹgẹ fun awọn onimọto tasi (taxi) ti nwọn nfẹ ki nwọn fọwọ lọ aṣẹ onikumọ yi nitoripe ko ba oju mu rara. Ẹ jẹki mọto ayọkẹlẹ wa kero l'Eko laisi idiwọ.

Aiye ominira ni gbogbo wa.

# Iwe Si Olotu

## A Nfe Itan Eko Akete Ile Ogbon

Ẹ jọwọ Olotu, a fẹ ki ẹ ba wa tun tẹ iwe itan EKO AKETE ILE ỌGBỌN ti opitan yin, Ọgbẹni Ọlalekan Ọnatade ti nfi igba kan kọ sinu iwe Eleti-Ọfẹ yin.

Itan na dara pupọ, o si jẹ ki ọpọlọpọ awa ti a ka awọn itan na mọ bi nkan ti ri ni ilu Eko ni aiye atijọ. Ọpọlọpọ awọn ẹmọ Yoruba ti nwọn ka awọn eyiti ọgbẹni opitan na kọ ni nwọn kan saara si i.

Inu wa yio dun bi ẹ ba le gba opitan na ni iyanju si wipe ki o tubọ kọ awọn itan na si fun anfani awọn ọdọmọde ti nwọn fẹ mọ bi aiye ti gbadun to ni Eko atijọ.

Porto-Novo, Emi ni,
Dah mey Alhaji M Raji

### Awon Oja Ilu Russia

Gbogbo ẹru ati ọja awọn Oyinbo ajoji kakiri gbo gbo agbaiye ni a ma nri n ṣọbu takiri ṣugbọn lati igbati a i gba ominira emi ko ti ri i ilu Russia kanṣoṣo ni ṣọbu awọn enia wa, ju awọn ti a ti ri nibi ipolowo ọja ti uwọn ee lesin ni eti Okun Alasia lọ.

Boya awọn eleto Ijọba wa ni ka fẹ ki ọja wọn ko wa silẹ yi rara ni tabi Kilo fa? A gbọ wipe awọn ọja wọn dara pupọ ju ti awọn Oyinbo miran lọ

Ẹ jọwọ, ẹ ba wa tẹ mọ awọn olotu Ijọba leti ki nwọn jẹki ẹru awọn Russia na ma wọ ilu fun tita.

Emi ni,
Mushin James Alao

AKIYESI:
A gbọ wipe Ijọba wa ti ba awọn Ijọba ilu Russia ṣe adehun laipẹyi, ki ọdun yi ko to Pari ẹru wọn bi moto akero, ẹrọ iroko ati awọn ọja bẹẹbẹ yio mawọ Nigeria lati ọdọ wọn.
OLOTU—


**Plushes, Velvet Velveteen Damask & Building Materials**

PLEASE COUNSULT

**Okunowo Brothers**

63, Massey Street, Faji Market
LAGOS NIGERIA.

The House Where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed.


# E Ka

**Irohin Aunti Koforun ti o kun fun Ogbon ati oye ni oju Ewe keta**

# Nihin Lohun Ati Nibi GbogbO

## Lati Owo Ayituka

## Konibaje

Ẹ jọwọ gbogbo ẹnyin ọkawe mi, ọrọ mi ko ni pọ pupọ lọsẹ yi nitoripe nko ni fẹ sọ oboto ọrọ nipa ọrọ nla kan ti o bẹ silẹ larin awọn oselu wa ni Ipinlẹ Iwọ Orun ni Iba an ti nwọn ti nfi igba kan ara wọn se aawo nipa ọrọ ilu, ti nwọn fi awọn ko tun ni ba ara wọn se rọọ, ti nwọu si tun ro ori wọn wo wipe awọu yio tun ba ara wọn ṣere.

Ọbẹ ki tinu agba mi, ẹnu emi Ayituka kọ ni ẹ o ti gbọ wipe iya Kọla laje; ṣugbọn ju gbogbo rẹ lọ, a dupẹ pupọ lọwọ agbalagba ti nwọn ba awọn oselu nwọnyi da mọran wipe ki nwọn ma jẹ ki AIYE YORUBA BAJẸ jubi o ti nwọ lọ yi.

Ẹnyin ọrẹ mi, AIYE NA KO NI BAJẸ O, ṣugbọn ki nwọu jẹki gbogbo wa ṣere pọ.

### Omo Bolumole

Ẹyin ọrẹ mi, ori lo mọ ibiti ẹsẹ nre, nkan ti o jẹ ki nsọ ọrọ yi ni ti arabinrin wa kan, Comfort Subuọla aya Jọda (ọmọ Bolumọle ni Itoku ni Abẹokuta) ti o jalaisi l'Eko ninu ọsẹ ti o kọja yi. Abẹokuta ni ile baba rẹ ni o wa ki o to se aisan fẹrẹ, ṣugbọn ori rẹ sọ wipe Eko ni yio sun.

(Wo iyoku ni oju ewe kejọ)

# Ile Adete Uzuakoli Ko Si Dokita Fun un Mo

ORON -- Irohin nla kan ni gbogbo awọn ara Ipinlẹ Ila-orun gbọ ninu ọsẹ yi ti o ṣe ni lanu-rohin na ni ti awọn ile iwosan awọn Ijọ Ṣọṣi Methodist ti o wa kakiri gbogbo Ipinlẹ na ti nwọn ngbero lati ti wọn pa nitori awọn dokita enia dudu ti nwọn ko ri lati wa ma se iṣẹ nibẹ.

Eyi ti o tilẹ jẹ pataki nibẹ ni ile iwosan awọn adẹtẹ ti awọn Ijọ na kọ si ibi kan ti nwọn npe ni Uzuakoli leti Aba ti nwọn fi nṣe anu fun awọn adẹtẹ, ti nwọn ni nwọn le ti pa bamubamu nitoripe dokita enia-dudu kan ko fẹ ṣe iṣẹ alanu.

Akọwe onirohin wa ni pẹlu omi loju ni baba ara Moba kan ti o ni ẹbi nile iwosan awọn adẹtẹ na fi nrojọ fun oa wipe awọn ṣeṣẹ gbe ibatan on lọ si Uzuakoli ni ago awọn adẹtẹ fun itọju ni ki oa to gbọ wipe nwọn ni lati da ara-kunrin na pada wa sile ni ọdọ awọn nitoripe dokita ko si ti yio tọju wọn.

Dokita Ẹyọ Mọma tiṣe igbla koji alaga Ijọ Ṣọṣi awọn Methodist ti o ṣeṣẹ ti ilu awọn Hausa loke Oya de si Aba laipẹ yi ni o nṣe ikede yi. O ni o ya awọn lẹnu pupọ wipe ko si doktia ọmọ ilẹ Nigeria kan ti nwọn nṣe iṣẹ-anu lati wo aisan ti o nṣe awọn adẹtẹ.

Dokita Moma ni lẹta ni awọn nọsi (nurse) paapa, o ni awọn ẹgbẹ ilera agbaiye (WHO) ni awọn kọwe si nisisiyi, ti awọn mbẹ wọn wipe ki nwọn ba awọn wa dokita alawọ funfun ti nwọn yio ma ba awọn tọju awọn adẹtẹ nwonyi, bi ẹkọ a ṣe wipe awọn yio ti ago awọn adẹtẹ na pa bamu bamu niyen.

# Awon Ole Gbe Awon Onisuga Lowo Ni Ilorin

EKO—Awọn Oyinbo onisowo ṣuga ti nwọn ṣeṣẹ wa da iṣẹ ṣuga ti Ilorin ti wọ gawu lọdọ awọn ole agbewiri. Ni ijẹta ni awọn ọlọpa ko awọn akọwe mẹta ti banki ile ifowo pamọ ati telọ kan wa si Kotu niwaju adajọ kan l'Eko pẹlu ẹsun wipe nwọn ji ẹgba metalelogbọn pọnun (£66,000) gbe ninu owo ti awọn Oyinbo Onisẹṣuga na fi pamọ si Barclays Bank l'Eko.

Eleyi ni oruko awọn akọwe ile ifowe pamọ si na ti awọn ọlọpa ni awọn pẹlu awọn enia kan ni nwọn ji owo na : Lawrence Okeke, Adesina Willoughby, Justus Ojẹkunle ati ọgbẹni telọ kan ti nwọn npe ni Yesufu Bakare Yẹkinni,

Ọgbẹni G C Nonyelu tiṣe ọga awọn agbẹjọro Ijọba ni o sọrọ niwaju adajọ lọjọ ti nwọn ko awọn ọdaran na wa si Kotu.

Agbẹjọro na ni owo ti nwọn gbe na awọn Oyinbo kan ti nwọn npe ni Sugar Company Limited ni Ilorin ni nwọn nii, o ni o ku awọn ti nwọn jẹ babasalẹ fun awọn ọdaran na ti awọn ọlọpa nwa nisisiyi ti nwọn fẹ ko wọn wa si Kotu.

Agbẹjọro na tun se alaye fun adajọ wipe owo ti nwọn ji gbe na, nwọn ti fi pamọ si awọn banki mẹta miran l'Eko, awọn si ti mọ ibiti nwọn ko awọn owo na pamọ si, ki awọn ko awọn ti nwọn ran wọn lọwọ ṣe iṣẹ na wa si Kotu loku.

O ni ninu iwe ti nwọn fi ngbowo ni banki (Cheque Book) ni nwọn ti yọ awẹ ewe ti nwọn da orukọ Oyinbo ọga ibi iṣẹ na ti wọn npe ni Frazer si ti nwọn fi gba gbogbo owo gọbọyi bayi.

Lọya Ijọba na ni awọn fẹ ki adajọ paṣẹ ki nwọn si lọ fi awọn ọdaran na pamọ si ọgba ẹwọn fun ọsẹ mẹta na ki awọn le ribi ko awọn ẹgbẹ wọn yoku wa; adajọ kọ, o ni ọsẹ meji ninu yio yonda fun wọn ki nwọn fi mu wọn lọ pamọ na.

Nwọn ti ko awọn ọdaran na lọsi ọgba ẹwọn, wọn ko gba iduro awọn rara.

CARSON PAINTS AND VANISHES




SOLE AGENTS:

IKORODU TRADING COMPANY
20 & 28, Balogun Street, Lagos.

# Koforun

(O bere loju ewe keta)

ere bayi ti on ba ti le dawọ le e.

## Iya Agbese

Ọmọbinrin kan, ọmọ ọdun mejilelogun, Sally Jean Norie, ni Dokita Ward ti awọn ọlọpa yi mba ro ẹjọ fi igba kan ba on lo ninu oko ọlọla Lord Astor ni Clivedea Estate.

Ọmọge kon ti nwọn tun pe ni Iyaafin R ni ọmọge Keeler ni o mu on mọ Dokita na ki o to GBESẸ fun on loru ọjọ kan; iyaafin R na ni ninu ṣọbu ni on gbe ti nṣe iṣẹ ki Koforun ọrẹ on Keeler to mu on lọ sile ti nwọn ti ngbeṣẹ.

Margaret Richard ni orukọ obinrin ti o tun jẹri lẹhin eleyi. O ni gbogbo igba ti on ba lọ iwaju ninu ile Dokita Ward ni o ma nsọ fun on wipe ki on duro diẹ lati ba awọn ọmọ-jayejaiye ṣere.

### Baba Aseyun

O ni ti on ba si ti duro awọn ọkunrin ni on ma ba si ti nwọn ma nwọ ile; o ni bi nwọn ba si ti wọle, o ni ṣiṣe ko n... [illegible]

AWON NWO IYARA LATI LỌ GBE IṢẸ NIYẸN.

Ọmọge yi ni on niran ọjọ kan ti dokita yi ni ki on ba on wa enti o ba le ba ọmọ kan ṣe oyun ti ọmọ kau ni ninu awọn ti nwọn nwa gbe iṣẹ lọdọ awọn. Margeret ni on juwe ọrẹ on obinrin kan fun un.

Onirohin wa ni gbogbo awọn obinrin ti nwọn wa sọrọ ni Kotu na ni Dokita Ward na nfi owọ ya awọran wọn pelu aṣọ ti nwọn wọ sinu pali ti o gbe lọwọ ninu apoti awọn. ọdẹrẹ ti o gbe joko si

A gbọ wipe ọmọ Alufa Ṣọṣi kan ni ilu Oyinbo ni dokita ti awọn ọlọpa mba ro ẹjọ wipe o nfi AWỌN ASAPẸ sowo yi ati pe o si tun mba wọn lọwọ ninu nwọn nṣe oyun.

Ọrọ ẹjọ wọn na ka ti pari.

# Eleti-Ofe D'araba

# Oba Ilu Zanzibar Jalaisi

ZANZIBAR—Ọlọla Ọba Zanzibar ti orukọ rẹ nje Seyyid Sir Abdullah Bin Khalifa ti o gun ori oye ni idunta lẹhin ti baba rẹ Ọba ana jalaisi; ẹni ọdun mẹtalelaadọta ni Ọba na ṣe.

Irohin ti a gbẹ nipa amodi ranpẹ ti o ṣe ni wipe awọn dokita ti o ntọju rẹ rẹ ni ejẹ ti o ṣan lọ si atẹsẹ rẹ ko yege to nitorina awọn ni lati ge e lẹsẹ mejeji ni bi awọn ba fẹ k Ọba na ye.

Nitotọ awọn dokita na si ṣe iṣẹ ọbẹ fun un, Oyinbo dokita Gẹsi kan ti o mọ iṣẹ ọlọbẹ ṣe ni o ge ẹsẹ mejeji fuu ọba na ṣugbọn ko ye e rara.

Awọn ara ilu rẹ ni nkan ti o ya awọn lẹnu ni riri ti awọn ko nri ọba na ki o jade sita ti awọn ba nṣe nkan mọ, nwọn ni gẹgẹbi ọba Musulumi ko ni lati fara soko fun awọn rara ni ode ati ninu agbala afin rẹ.

# Pope Tuntun Gbadura Fun Ilu Afirika

ROME — Ẹni ọwọ Pope Paul kẹfa ti nwọn ṣẹṣẹ gbe fila ati ẹwu oye lọwọ gbadura nla fun gbogbo agbaiye ati awọn ara ilu Afirika ti o tun pe wọn ni ọrẹ on lọjọ ti nwọn nṣe ẹyẹ oye fun un ni ilu Rome

Gbogbo orişirişi awọn ikọ ni o wa sibi oye na lati gbogbo igun mẹrin agbaiye, Awọn Aguda ilu Nigeria marunlelọgọta ni nwọn wa sibi ti nwọn ti gbe fila de Pope tuntun na lori

Pope tuntun na ni inu on dun pupọ lati ri awọn ọmọ ijọ Ṣọṣi on ti nwọn ti ilu Nigeria wa si ibi ẹyẹ yi nitoripe ninu ọdun ti o kọja ni on lọ yẹ wọn wo ni ilu wọn nigbana on ko tilẹ ti mọ pe on yio di Pope rara.

Pope Paul kẹfa tuntun yi ni adura on ni ki aya gbogbo aiye ko balẹ, ki wahala ati ijangbọn ko kasẹ nilẹ ki ilu tutu fun ẹmọde tegba.



**Eni owo Alufa Ben O Bewaji (ni o wa lapa osi) ti Alufa Oyinbo ore re, John Brewer ti o mba a soro ninu awor a yi ti o fi owo ara re san owo oko alufa enia duda yi lati Ghana wa si ilu Oyinbo fun eko lori ise Sosi fun osu mefa. Alufa Brewer ni ko nse wipe on ni owo lowo pupo sugbon inu on dun ti on lo owo-ogun on si ona ti Oluwa fe, on ti fii sehun rere fun egbe on.**

# English Girl Will Study Hausa In Kano Market

LONDON—The first English girl ever to study for a degree in Hausa at London University is to spend her long vacation, starting on July 9, talking to stall holders ni Kano Market.

Twenty-years-old Miss Hannah Middleton, daughter of a former Mayor of Greenwich, London, is one of a trio of second year students in the African studies Department of the London School of Oriental and African Studies — all specialising in Hausa—who will be making the trip. Accompanying her will be a fellow English student, David Dalzel and an Indian student Mr Suneet Chopra.

'While we have the advantage at the London School of Oriental and African Studies of being able to talk to Nigerian Students in Hausa, all three of us feel we would benefit enormously by spending a vacation in Northern Nigeria in a place where we shall be speaking the language more or less al the time,' Miss Middleton explained to our correspondent yesterday.

Lecturers at the London School have drawn up a course of study for the students while in Kano. Their project is to study the loca products sold in Kano Market and compile a detailed list of Hausa names for the products together with notes on their origin, method of manufacture, use, price, and method of distribution.

After getting her degree, Miss Middleton would like to teach in Nigeria.

# Nigeria First For New British Jets

LONDON—Nigeria and Ghana will be the first countries to benefit when BOAC introduce their giant four-engined V.C.-10 jet liners early next year.

BOAC are to have twelve of the new aircraft which are designed primarily for operation to and from hot and or high airfields and although the first VC-10's will be officially delivered in February. Vickes-Armstrongs (Aircraft)- a member of the British Aircraft Corporation is making several available to BOAC before that date for route proving, development flying and training.

The first will go into passenger service on the Airline's Nigeria and Ghana routes early in April, it has been disclosed by Sir Basil Smallpeice, Managing Director of BOAC.

Initially, the VC 10's will fly seven times a week to West Africa rising to ten weekly flights in May.

In June June next year, the new jets will be introduced on the London-Canada routes and in July on East, Central and South African services. In August they will start twice-weekly services to South America.

# Nigeria Journalists With Lord Mayor Of Nottingham

NOTTINGHAM — Four Lagos journalists, visiting Britain as guests of tho Commonwealth Relations Office, were recçivad by the Lord Mayor of Nottingham on Monday. They spent the afternoon as his guests during a meeting of the City Council.

The journalists, who are spending a week visiting the North Midlands, are Mrs. Ada Agwu, ("Jane") of the West African Pilot, Mr. Ladipọ Fashade, production editor, Daily Express; Mr. Simeon Oluyẹmi, assistant features editor, the Morning Post, and Mr. Geoge Okoro, a sub-editor of the Daily Times.

The vistors arrived in Nottingham last Fri— ...r visiting a large ...rks in Scunthorpe, ...oinshire. They have since spent much of their time visiting schools-"Jane" to a girl's high school and Mr. Okoro and Mr. Oluyemi to a comprehensive boys' school equipped to insruct all standards of pupil from potential university entrants to mentally retarded boys.

'We were particularly impressed by the size and scope of the school's engineering department and its three gymnasia," Mr. Oluyemi told our correspondent yesterday.

A Nottingham journalist took Mr. Fashade on a visit to the local magistrate court, where he spent a morning studing court procedure.

# Northern Nigerian Women With New Ideas

LONDON — After touring Britain for six weeks ten Northern Nigerian women said they would be returning home on Friday "bubbling over with ideas" which they hoped they would be able to put to use.

The women have visited several British cities including London, Southampton, Manchester, Blackpool and Glasgow, studying hospitals, clinics, schools and welfare organisations during a tour organised by the British Council, at the request of the Northern Nigerian Government.

"We have seen so many things ... have intrested us sin... ame over," Malama Falmata Mani, the Matron of the secondary School at Maiduguri, told a correspondent. "In fact, we have got so many ideas it will take a bit of time to sort them out.

Another member of the party, Malama Amina Ibrahim a school teacher with the Sokoto N.A., hopes to return to study in Britain: "I should very much like to take a further teching course in this country, I feel there are so many things I could learn," she explained.




Facts speak for themselves. This venerable veteran, a truck type Lo 2000, vintage 1934, has covered 1,367,000 miles. No doubt it would have gone on if Daimler-Benz AG had not bought it back at the ripe old age of twenty-five. Of course not every Mercedes-Benz can have such a long working life. However, all Mercedes-Benz vehicles are built to last, just as much now as they were then, to give many years and many miles of trouble-free, economical service.

MERCEDES-BENZ

# LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS. (EB). IBADAN: KANO: KADUNA: JOS: POR" HARCOURT: ABA

SUB DISTRIBUTORS:

# ARMELS TRANSPORT LTD.

BENIN CITY: ONITSHA: ABA:


AYILUKA NI :

## Omo Bolumole Jalaisi

(O bẹrẹ loju ewe karun )

Isinku arabinrin na dun pupọ ninu ile aburo bale rẹ, Ọgbẹni Eman Adejare Jọda, ni opopo ita Ẹlẹyẹ ni Ita Faji l'Eko, gbogbo awọn ọmọ oloku, ẹbi ọkọ, Ologbe Samuel Ẹgbẹ Jọda ni nwọn pesẹ si bẹ.

Ile Isin Ijọ awọn Mẹtọdisti ni ita Tinubu ni nwọn ti ṣe isin oku na ki nwọn to gbe e lọ si itẹ ni Ikoyi.

Ayiluka ki ẹnyin ọmọloku, ẹku asẹhinde, ẹ si ku inawo, ẹhin oku a dara.

## Nwo" So Tshombe Di Edun Arinle

PARIS — Ina dilẹ lẹhin ajẹṣu; awọn ara ilu Congo ti sọ Ọgbẹni Moise Tshombe ti o ti igba kan ṣe Olotu Ijọba Ipinlẹ Katanga ri, di ẹdun arinlẹ fun ti Oye aṣiwaju na ti nwọn rọ ọ.

Ni ọjọ ọsẹ ti o kọja ni awọn ara ilu Congo na ṣe ajọdun kẹta ti wọn ti gba ominira, ṣugbọn ti nwọn ko roju raye ṣe.

Gbogbo igbati awọn ara ilu na njo ti nwọn nyọ yi Ọgbẹni Tshombe na wa ni idubulẹ amodi ninu ile awọn alaisan ni ilu Faranse nibi.

A gbọ wipe Tshombe paapa ti ṣọ fun akọwe rẹ wipe ki o ba on bẹ awọn olotu Congo ki nwọn fi iwe aṣẹ ifilu silẹ (passport) to yege ranṣẹ si on nitoripe awọn Oyinbo Faranse ko gba eyiti on mu lọwọ.

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosọkọ Street, Lagos, Box 467 Phone 23370; Editor: (Olotu) Ọla Ọnatade, 15, Kosọkọ Street, Lagos.